Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 188-201 | jan./ jun.2025.

# Ìdálùú Nìṣèlú: Láríjà Àkóónú Ọdún Ìbílẹ̀ Ọ̀pá ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà

# Controvérsia política: o conteúdo do Ano Tradicional do Cachorro nas cidades de Osi e Ipinsha

**Taiwo Ọpẹyẹmi AKINDUTI, PhD** *
ORCID iD https://orcid.org/0000-0001-9148-6656

**ÀṢAMỌ̀**
Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọdún Ọ̀pá gbéra sọ ní ìlú Osí tí ó wà ní ìhà àríwá Àkúrẹ́ ní ọdún 1419, kò sẹ́ni tó lè fi ìdí déètì pàtó tí ọdún náà bẹ̀rẹ̀ múlẹ̀. Orúkọ akọnikùnrin tí wọ́n ń fi ọdún Ọ̀pá bọlá fún ní ìlú Osí ni Akinlúùsẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ mọ̀ ọ́n sí Òrìṣà-Akin. Akọnibìnrin ni àwọn ará Ìpinṣà tí wọ́n ń gbé ní ìhà Gúsù Àkúrẹ́ ń bọlá fún ní tiwọn, orúkọ rẹ̀ ni Èyé-Mọ̀é. Àwọn akọni wọ̀nyí ni àwùjọ méjèèjì sọ di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ nítorí ipa mánigbàgbé tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn kó ní àwùjọ rẹ̀. Ẹgbàágbèje iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí onírúurú ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, ṣùgbọ́n iṣẹ́ kò tíì dunlẹ̀ lórí ìjọra àti ìyàtọ̀ tó hànde nípa àwọn ìgbésẹ̀, tó fi mọ́ ìpohùn tó ń wáyé nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ọdún Ọ̀pá ní Osí àti Ìpinṣà. Pẹ̀lú àmúlò tíọ́rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò, iṣẹ́ yìí gùn lé ọ̀rínkínniwín ìtọpinpin nípa àwọn ìlànà à-ń-tẹ̀lé tó forímù sínú ọdún kọ̀ọ̀kan, ó ṣe àyẹ̀wò láríjà onírúurú ìgbòkègbodò tó rọ̀ mọ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, pàápàá jù lọ, ìtọ́ka sí ohun tí ó wọ̀ ní ìlú kan gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò wọ̀ ní ìlú kejì, ó sì jíròrò lórí àwọn àkóónú tó pa ọdún méjèèjì pọ̀ àti àwọn tó yà wọ́n sọ́tọ̀. Ọgbọ́n ìṣèwádìí tí a gùnlé ni pé, a kópa nínú ọdún náà, a sì gba détà nípasẹ̀ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò. Orí èrò tí ìwádìí yìí gúnlẹ̀ sí ni pé bí ìlú méjì bá bá ara wọn tan, tí wọ́n bá sì ń ṣe ọdún tó ń jẹ́ orúkọ kan náà ní oṣù kan náà lọ́dọọdún, síbẹ̀ èrò ìran Yorùbá tó sọ pé, 'báyìí là ń ṣe nílẹ̀ yìí, èèwọ̀ ni ní ilẹ̀ ibòmíràn,' kò níí ṣàìfẹsẹ̀múlẹ̀ ṣinṣin sínú ìgbòkègbodò ọdún tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń ṣe.

**KÓKÓ-Ọ̀RỌ̀**
Ọdún Ìbílẹ̀, Yorùbá**,** Ọ̀pá jíjà, Akinlúùsẹ̀, Osí, Èyé-Mọ̀é, Ìpinṣà, Ìwúre

**RESUMO**
Pesquisas estabeleceram que o ano de Opa começou na cidade de Osi, localizada ao norte de Akure, no ano de 1419, embora ninguém possa confirmar a data exata de seu início. O nome do herói homenageado com o ano de Opa na cidade de Osi é Akinlùùssè, conhecido por muitos como Orìia-Akin. O povo Ipinsha, que vive ao sul de Akure, homenageia uma heroína, cujo nome é Èyé-Mòé. Esses heróis foram transformados em divindades por ambos os grupos devido ao papel inesquecível que cada um deles desempenhou em sua comunidade. Estudiosos têm trabalhado extensivamente sobre os vários festivais tradicionais iorubás, mas pouco se tem feito sobre as semelhanças e diferenças que emergem dos rituais, incluindo os rituais que ocorrem durante a celebração do festival de Opa em Osi e Ipinsha. Utilizando a teoria da perspectiva cultural, este trabalho amplia o escopo do estudo dos rituais que moldam cada festival, examina a interação das diversas atividades associadas a cada um e, em particular, discute as semelhanças e diferenças entre os dois festivais. A metodologia de pesquisa utilizada foi a participação no ano e a coleta de dados por meio de entrevistas. A premissa desta pesquisa é que, se duas cidades estão relacionadas e celebram um ano com o mesmo nome no mesmo mês todos os anos, a crença iorubá de que "é assim que fazemos neste

* Department of Yoruba, Faculty of Culture, The College of Humanities and Culture, Ikire Ọṣun State University, Oṣogbo, Nigeria. E-mail: taiwo.akinduti@uniosun.edu.ng

país, é proibido em outros países" não se perderá nas atividades anuais que cada uma delas celebra.

**PALAVRAS-CHAVE**
Ano Tradicional, Iorubá, Opa Jija, Akinluussae, Osi, Eyé-Moe, Ipinsha, Iwure

**Ìfáárà**

Ọdún ìbílẹ̀ ni a lè ṣe àpèjúwe gẹ́gẹ́ bí àpéjọpọ̀ tó ṣe àkójọpọ̀ tonílé-tàlejò láti pe àkíyèsí sí ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣodo sínú ọdún. Lára àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí ni ìbọlá-fúnni, àfihàn àṣà àti ìṣe, ìgbéláruge èrò àti ìgbàgbọ́, orò, oúnjẹ àwùjọ ọlọ́dún, ìmúra, àwọn ohun àmì, ìwúre àti àwọn àkóónú mìíràn. Ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá jẹ́ apá pàtàkì lára ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn, tí àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ fúnraa wọn àti àwọn ẹlẹ́sìn Ìsìláàmù, tó fi mọ́ àwọn ẹlẹ́sìn Kírísítì tí wọ́n gbà pé ìgbàgbọ́ kò pé kí a má ṣe orò ilé ẹni fi ọwọ́ pàtàkì mú nítorí ìgbàgbọ́ tí wọ́n ní nínú rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun àìgbọdọ̀-má-ṣe láti mú kí ìtẹ̀síwájú dé bá àwùjọ, láti wá ojútùú sí àwọn ìpèníjà àti àdojúkọ àwọn ènìyàn, láti fi ẹ̀mí ìmoore hàn fún ìbọ tí wọ́n fi ọdún náà sọrí rẹ̀ àti láti wá ojúrere ìbọ náà àti ti Olódùmarè.

Gbogbo ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ni àfojúsùn wọn rọ̀ mọ́ àwọn àkóónú ọdún tí a mẹ́nu bà wọ̀nyí. Nígbà tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa àṣà àti ìṣe Yorùbá, Ibrahim (2020:105) tọ́ka sí i pé “*they also have commonly shared festivals, customs and traditions*.” (ìjọra wà nínú ìgbòkègbodò ọdún ìbílẹ́, tó fi mọ́ àṣà àti ìṣe wọn). Adebua àti Ṣotunsa (2018:200) ní tiwọn sọ ojú abẹ níkòó pé “*many festivals in Yorùbáland are celebrated to ensure the health, unity and the general well-being of the people*.” (ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ìbílẹ̀ tí àwọn Yorùbá ń ṣe ní àwùjọ wọn ni àwọn ènìyàn náà ń ṣe láti rí i dájú pé wọ́n gbádùn ìlera pípé, ìṣọ̀kan àti gbogbo ohun tó le múni gbáyé-gbádùn).

Omigbule (2018:48) ṣe àkópọ̀ ọ̀rọ̀ yìí nígbà tó sọ pé “*Each festival dedicated to a deity is an occasion for the involvement of one or multiple deities in the task of confronting the challenges of existence*.” (àkókò tí ọ̀kọ̀ọ̀kan ọdún ìbílẹ̀ tí a fi sọrí òrìṣà ń wáyé ni a máa ń lò láti késí òrìṣà kan tàbí ọ̀pọ̀lọpọ̀ òrìṣà láti báni wá ojútùú sí àwọn ìpèníjà ìgbésí-ayé). Gbogbo ìgbòkègbodò ọdún ìbílẹ̀ ló máa ń kó onírúurú nǹkan tí àṣà àti ìṣe àwùjọ ọlọ́dún ìbílẹ̀ rọ̀ mọ́ bọnú, èyí a sì máa tan ìmọ́lẹ̀ sí ojú-àmúwayé àwọn ènìyàn náà. Obamwonyi àti Onyekuru (2024:4) tọ́ka sí i pé “*traditional festivals are rooted in indigenous cultures and are celebrated to honour nature, deities, ancestors, or specific ecological events*.” (inú àṣà ìbílẹ̀ àwùjọ ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ ti sú yọ, wọn a máa ṣe àwọn ọdún wọ̀nyí làti bọlá fún àyíká, àwọn òrìṣà, àwọn baba-ńlá tàbí àwọn nǹkan àyíká, tó fi mọ́ irúfẹ́ ìbáṣepọ̀ láàárín olúkúlùkù wọn).

Ọdún Ọ̀pá jẹ́ ọ̀kan gbòógì lára àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. Ìlú Osí àti ìlú Ìpinṣà wà lára àwọn ìlú tí wọ́n ti ń ṣe é ní ẹ̀ẹ̀kan lọ́dún. Oṣù Agẹmọ ni ọdún Ọ̀pá máa ń wáyé ní ìlú méjèèjì. Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Ìsẹ̀-Èkìtì ni orírun ọdún Ọ̀pá tí wọ́n ń ṣe ní ìlú Osí àti ìlú Ìpinṣà. Ararọba (2019:103) ṣe àlàyé pé :

> Ìlú Ìsẹ̀-Èkìtì ni orírun ọdún Ọ̀pá tí wọ́n ń ṣe ní ìlú Ìpinṣà, ìlú Osí tí ó yapa kúrò lára Ìsẹ̀-Èkìtì ni ọdún náà ti tàn lọ sí ìlú Ìpinṣà . . . síbẹ̀ kò sí Ìbáṣepọ̀ kankan láàrin Ìsẹ̀-Èkìtì àti Ìpinṣà. Ààrín ìlú Osí àti ìlú Ìpinṣà ni ìbáṣepọ̀ ti wáyé nípasẹ̀ ìgbéyàwó.

Àyọlò òkè yìí mú kí ó hàn gbangba pé Ìsẹ̀-Èkìtì ni ọdún ìbílẹ̀ Ọ̀pá ti ṣẹ̀, lẹ́yìn náà, ó rékọjá sí Ìpinṣà nípasẹ̀ ìlú Osí. Ìtàn ìwáṣẹ̀ fi yéni pé apá kan Ìsẹ̀ ni àwọn ènìyàn àwùjọ tí a mọ̀ si Osí lónìí kí ó tó di pé awuyewuye tí ó wáyé lórí ìfọbajẹ ní ìlú Ìsẹ̀ mú kí ọmọ oyè tí ó jẹ́ ẹ̀gbọ́n fi ìlú Ìsẹ̀ sílẹ̀ pẹ̀lú àwọn alátìlẹyìn rẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n fi àbúrò rẹ̀ jẹ ọba. Ìwádìí fi hàn pé

onírúurú ilẹ̀ ni àwọn ènìyàn náà tẹ̀dó sí kí ó tó di pé wọ́n pinnu láti tàkàn mọ́lẹ̀ sí ibi tí a mọ̀ sí Osí lónìí. Apá àríwá ní ìlú Àkúrẹ́ ní Ìpínlẹ̀ Oǹdó ni ìlú Osí wà. Atánmúdè tíí ṣe ọba kẹrin ní ìlú náà ni ó bí Èyé-Mọ̀é tó di aya ní ìlú Ìpinṣà fún Akápinṣà kìn-ín-ní tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ẹ̀kíkẹ́jẹ̀ẹjẹ̀jẹ̀. Èyé-Mọ̀é tíí ṣe ọmọ-ọbabìnrin ìlú Osí ni ó mú ọdún Ọ̀pá lọ sí ìlú Ìpinṣà. Ararọba (2019:103) tọ́ka sí i pé "ọdún ilé ọba ni ọdún Ọ̀pá jẹ́ ní ìlú Ìsẹ̀-Èkìtì" Bí a bá wo sàákun nípa ọ́nà tí ọdún ìbílẹ̀ náà tọ̀ láti ìlú Ìsẹ̀ lọ sí Osí títí tó fi dé Ìpinṣà, a óò rí àrísá pé ọdún ilé ọba ni ọdún náà ṣì jẹ́ síbẹ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé lẹ́yìn tí Atánmúdè fi ìkàlẹ̀ sí ìlú Osí, ó tẹ̀ síwájú láti máa ṣe ọdún ilé bàbá rẹ̀. Bákan náà, ipasẹ̀ ọmọ-ọbabìnrin tí ó di ayaba ní Ìpinṣà ni ọdún náà gbà dé Ìpinṣà.

Àpilẹ̀kọ yìí ṣe àyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ ìlànà à-ń-tẹ̀lé nínú àgbékalẹ̀ ọdún Ọ̀pá ní ìlú Osí àti Ìpinṣà. Ó tọpinpin àwọn ìgbòkègbodò tó rí bákan náà nínú ọdún méjèèjì, ó sì ṣe àfihàn àwọn ohun tó ya àgbékalẹ̀ ọdún ìbílẹ̀ Ọ̀pá sọ́tọ̀ ní Osí àti Ìpinṣà.

**Tíọ́rì Àmúlò**

Tíọ́rì àmúlò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ni ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014) pe tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ní lámèétọ́ àṣà nínú iṣẹ́ rẹ̀. Nígbà tó ń sọ̀rọ̀ nípa lámèétọ́ àṣà, Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014:60-62) sọ pé: "àkọ́ọ́lẹ̀ Preminger àti Brogan (1993:262) fi yéni pé láti ọ̀rúndún kejìdínlógún tí lámèétọ́ àṣà ti di dídásílẹ̀ ni ọ̀rọ̀ nípa àwọn àkíyèsí ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ti múmú láyà wọn…" Àwọn àkíyèsí tí Ọ̀pẹ́fèyítìmí tọ́ka sí pé wọ́n jẹ àwọn onítíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò lógún jẹ́ márùndínlógún. Lẹ́yìn ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn àkíyèsí wọ̀nyí lẹ́yọ kọ̀ọ̀kan, mo ṣe àṣàyàn márùn-ún tí mo gbà pé yóò tan ìmọ́lẹ̀ sí àwọn àkóónú onírúurú ìpohùn tí mo yàn láti ṣàmúlò nínú àpilẹ̀kọ yìí. Àwọn àkíyèsí máràárùn ló wà ní ìsàlẹ̀ yìí, gẹ́gẹ́ bí Ọ̀pẹ́fèyítìmí ṣe ṣe àgbékalẹ̀ wọn:

a. Àwọn àǹfààní tó wà fún àyípadà àwùjọ
b. Àwọn ọ̀nà tí onírúurú nǹkan fi ń tàn kálẹ̀.
d. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí ìṣèlú tó jẹ mọ́ àwọn nǹkan ìṣẹ̀ǹbáyé, ìṣẹ̀lẹ̀, ìṣe àti onírúurú ẹgbẹ́ láwùjọ fi tọ súnà.
e. Àwọn ìlànà ìgbàmúṣẹ́ṣe tó kan ìtúpalẹ̀ afọ̀, ìwoṣàákun àti ìlànà ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò, ìṣèwádìí nípa ìtàn-ìrírí-ẹ̀dá pẹ̀lú ìtúpalẹ̀ àwọn àgbékalẹ̀ àti ojú tí àwọn èèyàn fi ń wo báyéṣerí.
ẹ. Ohun tí a ṣe àti ìlànà tí a gbà ṣe é

Yàtọ̀ fún Preminger àti Brogan, àwọn mìíràn tí wọ́n tún jẹ́ agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ni Matthew Arnold àti Edward B. Tylor. Nínú ìwé tí ó pè ní *On Culture: Matthew Arnold's Culture and Anarchy, 1869*, Logan (2012) ṣàlàyé pé tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò tí Arnold ṣe agbátẹrù rẹ̀ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò méjì tí ó sú yọ ní nǹkan bí 1870. Matthew Arnold jẹ́ ọmọ bíbí inú gbajú gbajà olùkọ́ kan, Thomas Arnold (1795-1842). Ní ìwòye Thomas Arnold, ó ṣe pàtàkì pé kí ohunkóhun tí ó bá jẹ́ àfojúsùn ènìyàn kan ṣe àwùjọ ní àǹfààní. Ó gbà pé kì í ṣe ohun tí ó bójú mu bí àfojúsùn ẹni kan bá dá lórí ohun tí ó lè wúlò fún òun nìkan. Matthew Arnold fara mọ́ èrò yìí, bí ó ṣe jà fitafita láti rí i dájú pé ìfẹ́ rẹ̀ fún iṣẹ́ ọnà kò ṣe ìdíwọ́ tàbí mú àdínkù dé bá ipò tí ó yẹ kí ó to àwùjọ sí jẹ́ ẹ̀rí máa-jẹ́mi-nìṣó. Èyí túmọ̀ sí pé ìdílé tí a ti tọ́ Matthew Arnold dàgbà ní ipa lórí ojú tí ó fi wo àṣà àti àwùjọ.

Ẹ̀kọ́ nípa ènìyàn àti àṣà ni iṣẹ́ Edward B. Tylor dá lé lórí. Agbo ilé Kìrìsìtẹ́nì tí wọ́n ti gbàgbọ́ nínú ìgbé ayé ìrọ̀rùn, tí wọ́n sì ní ìfọkànsìn, ni wọ́n gbé tọ́ Tylor dàgbà. Bíi ti Arnold, ilé tí wọ́n ti tọ́ Tylor dàgbà ní ipa lórí ohun tí ó kà sí àṣà. Ìdílé Tylor gbàgbọ́ pé ó ṣe pàtàkì láti rí àwùjọ ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan ṣoṣo, wọ́n gbà pé irúfẹ́ ojú àmúwayé báyìí lè ṣe atọ́kùn fún ìṣọ̀kan àti àlàáfíà. Àlàyé nípa ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ènìyàn títí di ìgbà tí ọ̀làjú dé àwùjọ ni Tylor ṣe iṣẹ́ lé lórí. Tylor ṣe àpèjúwe àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí àwọn ìgbòkègbodò àwùjọ dá lé

lórí. Lára wọn ni ìgbàgbọ́, iṣẹ́-ọnà, ìwà, òfin àti àwọn ìlànà mìíràn ti àwùjọ gbé kalẹ̀. Nígbà tí Logan (2012:1) ń sọ èrò rẹ̀ nípa àpèjuwe tí Tylor ṣe nípa àṣà, ó ní "here, culture refers to the learned attributes of society, something we already have." (àṣà jẹ́ àwọn ohun àmúyẹ tí àwùjọ fi kọ́ni, ohun kan tí ènìyàn ti ní). Ní ìwòye Logan, ohun tí àwùjọ fi kọ́ni, tí ènìyàn sì ti sọ di tirẹ̀ ni àpèjúwe tí Tylor fún àṣà tọ́ka sí.

Tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò tí Arnold ṣe agbátẹrù rẹ̀ gbàjú mọ́ àwọn ohun àmúyẹ tí àwùjọ fi ń kọ́ni, tí ó ṣe pàtàkì kí ènìyàn ní. Ó ní èyí yóò ṣèrànwọ́ láti mú ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ. Ìtakora wà nínú èrò Tylor àti Arnold. Ìdí ni pé, ní ìwòye Tylor, ọ̀nà ìgbé ayé tí àwùjọ ní, tí ó sì ń ṣe àmúlò ni ó ń jẹ́ àṣà. Àmọ́, Arnold ní tirẹ̀ gbà pé ọ̀nà ìgbé ayé tí ó ti wà ní àwùjọ, tí ó yẹ kí ènìyàn kọ́, kí ó sì ṣe àmúlò rẹ̀ ni àṣà. Yálà àṣà jẹ́ ohun tí ènìyàn tí ń ṣe àmúlò rẹ̀ léraléra tàbí ohun tí ó yẹ kí ènìyàn kọ́, kí ó sì máa mú lò, àkíyèsí Logan nípa àwọn agbátẹrù tíọ́rì méjèèjì ni pé oko kan náà ni wọ́n ń ro láti kojú èrò tí kò tọ̀nà tí àwọn ènìyàn ní nípa àṣà. Yàtọ̀ fún èyí, ó pe àkíyèsí sí àtiwáyé tíọ́rì méjèèjì ní sáà kan náà. Logan (2012:1) ṣe àlàyé pé:

> The simultaneous appearance of the two theories of culture suggests a connection between them, and in fact both versions of culture had an overlapping interest in responding to one and the same problem. Each redefined culture from a term limited to individuals to one that encompassed society as a whole.
>
> (Àtiwáyé tíọ́rì méjèèjì ní àsìkò kan náa mú kí ó jọ bí ẹni pé ìbáṣepọ̀ wà láàrin wọn, ká sòótọ́, àwọn méjèèjì ni a gbé kalẹ̀ láti wá ojútùú sí ìṣòro kan ṣoṣo, tí ó rí bákan náà. Ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ṣe àtúnṣe sí àpèjúwe àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó jẹ mọ́ ẹni kọ̀ọ̀kan, wọ́n ṣe àpèjúwe àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó jẹ mọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ lápapọ̀)

Àlàyé Logan yìí fi yéni pé láríjà tíọ́rì méjèèjì ni láti ṣèrànwọ́ fún àwọn ènìyàn àwùjọ tí èrò wọn kò tọ̀nà nípa ohun tí àṣà túmọ̀ sí, kí wọ́n ba lè mọ ohun tí àṣà jẹ́ ní tòótọ́.

Àṣà àwùjọ ni tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò fúnka mọ́. Abímbọ́lá (1977:13) ṣàlàyé pé:

> The cultural approach must be adopted for the analysis of Yorùbá literature. Literature is culture and no literature can be meaningfully analysed outside the facts of the culture which produced it.
>
> (Ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ni a gbọ́dọ̀ ṣàmúlò fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Àṣà ni lítíréṣọ̀, kò sí lítíréṣọ̀ tí a le tú palẹ̀ lọ́nà tó nítumọ̀ láìjẹ́ pé a mọ òtítọ́ tó rọ̀ mọ́ àṣà tí ó bí i)

Onímọ̀ yìí sọ ojú abẹ níkòó pé tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ṣe pàtàkì púpọ̀ fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ó fi kún un pé ẹni tí kò bá ní ìmọ̀ tó péye nípa àṣà tí ó bí lítíréṣọ̀, kò lè tú lítíréṣọ̀ palẹ̀ lọ́nà tó múná dóko. Èyí fi hàn pé bí ìgbín kò ṣe lè wà láàyè láìsí ìkarahun ni lítíréṣọ̀ kò lè wà láìsí àṣà nítorí pé àṣà ni okùnfà àtiwáyé lítíréṣọ̀. Lára àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò tẹpẹlẹ mọ́ ni a ṣe ìsọníṣókí wọn ní ìsàlẹ̀:

a. Níní àwùjọ lọ́kàn nígbà tí a bá fẹ́ dáwọ́ lé ohun kan.
d. Pàtàkì gbígbé ìgbésẹ̀ tí yóò ṣe àwọn ènìyàn àwùjọ ní àǹfààní.
e. Mímú àyípadà tí ó dára bá àwùjọ.
ẹ. Gígún régé àwùjọ jẹ́ àbájáde ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn ènìyàn inú rẹ̀.
f. Ìfẹ́ àti ìṣọ̀kan a máa dènà ìyapa tàbí ìhùwàsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà.

Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ wọ̀nyí hànde nínú ìtúpalẹ̀ détà tí mo ṣe nínú àpilẹ̀kọ yìí.

**Ìmúrasílẹ̀ fún Ọdún *Ọ̀pá* ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà**

Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn ènìyàn ìlú Osí létò púpọ̀. Fún ídí èyí, láti nǹkan bí oṣù mẹ́ta ṣáájú oṣù Agẹmọ tí ọdún Ọ̀pá yóò wáyé ni wọn yóò ti máa palẹ̀mọ́ fún ọdún náà. Ìdí tí wọ́n fi fi ọwọ́ pàtàkì mú ìmúrasílẹ̀ fún ọdún ni pé wọ́n fẹ́ kí ohun gbogbo lọ létòlétò. Ní ọ̀sẹ̀ tí ọdún Ọ̀pá yóò wáyé, àwọn ọdẹ yóò dẹ ìgbẹ́ lọ láti pa ẹran ọdún, àwọn àgbẹ̀ yóò wa ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣu, wọn yóò sì kó wọn wálé. Wọn a ká obì, wọn a sì ká awùsá wálé. Àwọn tí ń dá ẹmu náà yóò kó ipa tiwọn, nítorí pé, yàtọ̀ fún pé àwọn ènìyàn yóò mu ún láti ṣe fàájì ní àsìkò ọdún, ẹmu jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn èròjà ọdún Ọ̀pá. Ohun èlò tí ó ṣe pàtàkì jù lọ̀ fún ọdún Ọ̀pá ni a mọ̀ sí pàṣán. Pàṣán yìí ni àwọn ará Osí àti ará Ìpinṣà ń dà pè ní ọ̀pá tàbí igi. Kódà, òun ni wọ́n fi ń pe ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n ń ṣe láti bọlá fún, àti láti ṣe ìrántí Akinlúùsẹ̀ tí a tún mọ̀ sí òrìṣà-Akin àti Èyé-Mọ̀é. Ní ọ̀sẹ̀ tí ọdún náà yóò wáyé, ó pẹ́ tán, ọjọ́ mẹ́ta ṣáájú àyájọ́ ọdún, ìyẹn ọdún di ọ̀túnla, ni àwọn ọ̀dọ́kùnrin yóò ti wọ inú igbó láti wá ọ̀pọ̀lọpọ̀ pàṣán tí wọ́n ti gbó káká, wọn a tún wá pàṣán tí kò fi bẹ́ẹ̀ gbó, kódà, wọn a máa wá àwọn pàṣán tí kò gbó rárá. Àkíyèsí ni pé àwọn pàṣán tó ti gbó dáradára ni ó sábà máa ń pọ̀ jù nítorí pé àwọn abarapá ló sábà máa ń fi ìfẹ́ hàn láti jẹ pàṣán. Ìdí tí wọ́n fi máa ń wá àwọn pàṣán tí kò fi bẹ́ẹ̀ gbó ni pé àwọn ọmọdé náà a máa kópa nínú ọ̀pá jíjà. Àwọn pàṣán tí kò gbó rárá wà fún àwọn ọmọ-ọwọ́.

Yàtọ̀ fún èyí, àwọn ọkùnrin a tún máa ṣiṣẹ́ takuntakun láti tún òpópónà ṣe, kí ó ba lè ṣe é ṣe fún àwọn àlejò láti rin ọ̀nà náà pẹ̀lú ìrọ̀rùn- yálà nínú ọkọ̀, lórí kẹ̀kẹ́ tàbí lórí alùpùpù. Kódà, àwọn tí yóò fi ẹsẹ̀ rìn kò níí máa já sí kòtò, já sí gegele nítorí àtúnṣe tí àwọn ọ̀dọ́ yóò ti ṣe sí àwọn ọ̀nà ṣíṣe kókó ṣáájú ọjọ́ ọdún. Bí ọwọ́ àwọn ọ̀dọ́kùnrin bá ṣe ń dí pẹ̀lú ìpèsè àwọn nǹkan tí àwọn akópa nílò, tó fi mọ́ onírúurú ètò àtúnṣe tí wọ́n ń ṣe, bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn àgbà ọkùnrin, pàápàá jù lọ àwọn olóyè mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí wọ́n wà ní ìgbọ́nnu ọdún Ọ̀pá, àti àwọn ìwàrẹ̀fà yóò ti máa ṣe onírúurú ìpàdé pẹ̀lú kábíyèsí láti rí i dájú pé ohun gbogbo lọ létòlétò. Ní ọjọ́ tí ó ṣáájú àyájọ́ ọdún, àwọn onílù yóò rí i dájú pé ìlù wà ní ipò tí yóò fi dún bí ó ṣe yẹ kí ó dún, bákan náà ni agogo.

Àwọn obìnrin náà kò gbẹ́yìn nínú ìpalẹ̀mọ́ fún ọdún Ọ̀pá. Àwọn àgbà obìnrin ìlú, àwọn olóyè obìnrin, tó fi mọ́ àwọn ayaba ni wọn yóò ti ṣe onírúuru ètò nípa wẹ̀jẹ-wẹ̀mu, bákan náà wọn yóò bojútó àwọn ọ̀dọ́bìnrin tí wọn yóò ṣe iṣẹ́ ìmọ́tótó ní àwọn ibi tí àwọn akópa yóò lò ní ọjọ́ ọdún. Abala tí ó wúni lórí jù lọ ni pé àwọn òbí, pàápàá jù lọ àwọn ìyá, a máa tẹ̀ ẹ́ mọ́ àwọn ọmọ wọn létí láti takété sí ìwà abèṣe ṣáájú, ní àsìkò àti lẹ́yìn ọdún Ọ̀pá. Èyí a sì máa dákún àlàáfíà àwùjọ náà. Kódà, ìkìlọ̀ yìí hàn nínú ọ̀kan lára àwọn orin ọdún tó lọ báyìí pé:

Lílé: Ọdún Ọ̀pá mò dọ̀la ò
Ègbè: Yeye ọmọ wí a ọ́lọ́mọ
Lílé: Ọdún Ọ̀pá mò dọ̀la ò
Ègbè: Yeye ọmọ wí a ọ́lọ́mọ

(Lílé: Ọdún mà dọ̀la ò
Ègbè: Kí ìyá ọmọ kìlọ̀ fún ọmọ rẹ̀ kí ó má ṣe fa ìjàngbọ̀n
Lílé: Ọdún mà dọ̀la ò
Ègbè: Kí ìyá ọmọ kìlọ̀ fún ọmọ rẹ̀ kí ó má ṣe fa ìjàngbọ̀n)

Nínú àgbékalẹ̀ àyọlò orin yìí, ìyá ni àwọn ọ̀kọrin, tí àwọn náà jẹ́ obìnrin dojú ọ̀rọ̀ kọ, ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ìran Yorùbá gbà pé nínú àwọn òbí méjèèjì, ìyá ló sùn mọ́ ọmọkùnrin tàbí ọmọkùnrin rẹ̀ jú lọ, òun ni yóò sì fi ojú winá èyí tí ó pọ̀ jù nínú ọ̀ràn tí ọmọ rẹ̀ bá dá.

Wọ́n gbà pé ọmọ burúkú ni ti iyá rẹ̀. Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé irúfẹ́ ìránnilétí báyìí a máa so èso rere.

**Dídá Ọjọ́ Ọdún, Ṣíṣe Ètùtù àti Wíwúre ní Ìlú Osí àti Ìpinṣà**

Bí ó bá ti ku ìtàdógún (ọjọ́ mẹ́tàdínlógún) kí ọdún Ọ̀pá bẹ̀rẹ̀ ni àwọn ará ìlú Osí yóò ti máa sọ ní ààrín ara wọn pé ọdún Ọ̀pá di ìtàdógún, nítorí pé ìtàdógún ni wọ́n máa ń dá fún ọdún náà. Àyájọ́ ọjà Ẹlẹ́yọwó ni àwọn ará ìlú Osí tẹ ìlú náà dó. Nítorí náà gbogbo ọdún tí wọ́n bá fẹ́ ṣe gbọ́dọ̀ bọ́ sí àyájọ́ ọjà náà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí Ifá sọ.

Nígbà tí ó bá ti ku ọjọ́ mẹ́sàn-án kí ọdún Ọ̀pá bẹ̀rẹ̀, wọn a bọ òrìṣà Akinlúùsẹ̀. Àgbò ni wọ́n máa ń pa láti bọ òrìṣà Akin. Àwọn olóyè mẹ́rin tí wọ́n wà ní ìgbọ́nnu ọdún náà ni Elégìrì, Olókorùn, Olórógbè àti Olótùú Àjíòre. Elégìrì ni ó ni ìlù lílù, ijó jíjó àti orin kíkọ. Alẹ́ ọjọ́ kẹsán-án yìí Elégìrì yóò ta ẹmu sílẹ̀, yóò sì wúre sí agogo àti ìlù bẹ̀ǹbẹ́. Yóò ta ẹmu sílẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì, yóò wá bẹ̀rẹ̀ sí í wúre:

Elégìrì: Akinlúùsẹ̀, ọ̀rìṣà ulé àba mi,
Ọdún Ọ̀pá ti yàa bẹ̀rẹ̀,
Kú ọ bá a bẹ̀rẹ̀
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Kú o bá a parí
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Agogo ọdún á ró,
Ùro ayọ̀ á ró lúlé ria
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Agogo ọdún í á a ró,
Ùro ùdùnnú á ró lọ́dẹ̀dẹ̀ kete ria
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Ùwúrí àtunú dídùn
Li dídún ùlù ú mú báni,
Ùlù ọdún á a dún, ùbànújẹ́ á fò lọ
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Ùlù ọdún i á a dún,
Ẹkún òun òṣé á dòrírá
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Kete ọni ko gbọ́ dídún ùlù àtagogo lá a ṣùmọ́dún
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Ọdún ko yàa bẹ̀rẹ̀ í,
Á a san olúlé
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Ọdún Ọ̀pa í, á a san àlojò
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Kete ria lá a ṣùmọ́dún láyọ̀ láyọ̀
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ

(Elégìrì: Akinlúùsẹ̀, òrìṣà ilé bàbá mi,
Ọdún Ọ̀pá ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀,
Kí o bá wa bẹ̀rẹ̀
Àwọn Ègìrì: Àṣẹ
Elégìrì: Kí o bá wa parí

Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Agogo ọdún yóò dún,
Ìró ayọ̀ yóò dún ní ilé wa
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Agogo ọdún yìí yóò dún
Ìró ìdùnnú yóò dún ní ọ̀dẹ̀dẹ̀ gbogbo wa
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Ìwúrí àti inú dídùn
Ní dídún ìlú ń mú báni
Ìlù ọdún yóò dún, ìbànújẹ́ yóò fò lọ
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Ìlù ọdún yìí yóò dún,
Ẹkún òun òṣé yóò pòórá
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Gbogbo ẹni tó gbọ́ dídún ìlù àtagogo ni yóò ṣàmọ́dún
Àwọn Ègirì: Àṣẹ

Elégirì: Ọdún tí ó fẹ́ bẹ̀rẹ̀ yìí,
Yóò san onílé
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Ọdún Ọ̀pa yìí, yóò san àlejò
Àwọn Ègirì: Àṣẹ
Elégirì: Gbogbo wa ni yóò ṣe àmọ́dún láyọ̀ láyọ̀
Àwọn Ègirì: Àṣẹ)

Lẹ́yìn ètùtù àti ìwúre tí wọ́n ṣe sórí ìlù bẹ̀ǹbẹ́ àti agogo, Elégirì yóò tún ta ẹmu sílẹ̀, lẹ́yìn náà, àwọn ènìyàn yóò sì bẹ̀rẹ̀ sí mu ún. Nígbà tí ìwúre àti ètùtù bá ti wá sí ìparí, wọn yóò bẹ̀rẹ̀ sí lu ìlù bẹ̀ǹbẹ́ àti agogo. Iwájú ilé Elégirì ni wọn yóò ti kọ́kọ́ lù ú, wọn yóò pagbo eré síbẹ̀ fún nǹkan bí wákàtí méjì, wọn yóò sì dá ìlù lílù dúró. Bí ọdún náà bá ti ku ọjọ́ méje, wọn yóò tún kó ìlù àti agogo síta. Lọ́tẹ̀ yìí, wọn yóò ṣeré kọjá iwájú òde Elégirì. Wọ́n yóò ya ilé Olórógbè, wọn a ṣe ìbẹ̀wò sí ilé Olókorùn, kí wọn tó tẹ̀ síwájú sí ọ̀dẹ̀dẹ̀ Olótùú Àjíóre. Lẹ́yìn náà, wọn yóò padà sílé. Bí ọdún Ọ̀pá bá ti kú ọjọ́ márùn-ún, wọn yòò tún ṣeré tẹ̀ síwájú. Bí ọdún bá ku ọjọ́ mẹ́ta, wọn a tún lùlù káàkiri. Ọwọ́ alẹ́, ní nǹkan bí aago méjọ sí mẹ́sàn-án ni ìlù lílù yìí máa ń wáyé. Irúfẹ́ ìmúrasílẹ̀ wọ̀nyí ni wọ́n ń pè ní "kíkulẹ̀ ọdún Ọ̀pá."

Bí ọdún Ọ̀pá bá ti ku ọ̀la ni àwọn ará ìlú yóò ṣe àìsùn ọdún Ọ̀pá títí di ọjọ́ kejì tí ọdún yóò sì bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹwu. Olóòtú Àjíóre, ọ̀kan lára àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá ni ó máa ń kó àwọn ènìyàn káàkiri ní alẹ́ tí ó kángun sí òwúrọ̀ ọjọ́ ọdún Ọ̀pá. Wọn a máa kọ orin, wọn a máa lu ìlù, wọn a sì máa jó láti fi ìdùnnú wọn hàn pé ojú tún rí ọdún. Ìdáwọ̀ọ́ ìdùnnú yìí yóò tẹ̀ síwájú títí di àfẹ̀mọ́jú ọjọ́ ọdún gan-an, olúkúlùkù yóò sì gba ilé rẹ̀ lọ.

Ní ìlú Ìpinṣà, Ẹrẹ́nà (oṣù kẹta) nínú ọdún ni àwọn ìpàdé tàbí àjọ kíkó ti máa ń bẹ̀rẹ̀. Èyí máa ń wáyé ní ìmúrasílẹ̀ fún àyájọ́ ọdún Ọ̀pá tí yóò kò ní Agẹmọ (oṣù keje). Onírúurú ẹgbẹ́ ni ó máa ń ṣe ìpàdé ní ìmúrasílẹ̀ fún ọdún Ọ̀pá. Lára wọn ni ẹgbẹ́ Àjíóre, ẹgbẹ́ Òkorùn àti ẹgbẹ́ àwọn obìnrin. Èyélóbìnrin tíí ṣe olórí gbogbo obìnrin ìlú ni ààrẹ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin. Òun ni ó kọ́kọ́ ń gba ìpàdé. Ní ìgbà tí ọjọ́ mẹ́sàn-án yóò bá fi yípo, àtẹ̀lé yóò gba ìpàdé tirẹ̀. Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀, ìpàdé yóò kan púpọ̀ nínú àwọn ọmọ ẹgbẹ́. Nígbà tí ó bá ku ọjọ́ mẹ́sàn-án kí ọdún Ọ̀pá bẹ̀rẹ̀, gbogbo ìpéjọpọ̀ fún ọdún Ọ̀pá yóò kásẹ̀ nílẹ̀. Lẹ́yìn tí onírúurú àjọ bá ti wá sí ìparí, ìpalẹ̀mọ́ fún ọdún náà yóò bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Ní ọjọ́ kẹsàn-án yìí, kábíyèsí yóò pa màlúù tàbí ewúrẹ́ tí ẹ̀yìn rẹ̀ gba igbá láti ṣètùtù, yóò sì ṣe ìwúre oríkádún fún gbogbo ìlú:

Olódùmọrè, ọba ko ba lórí kete ayé,
A ké pè ọ́,
Kú o dákun dábọ
Jọ́dún Ọ̀pá ria kò láyọ̀ ò
Kú o ṣàtìleyìn kÈyé Mọ̀é,
Káaboyún ulé bí wẹ́rẹ́;
Káàgàn tọ́ọ̀ àlà bosùn,
Kí i homọ yè;
Kọ́ọdún Ọ̀pá mire yí hòlú;
Kún un mó ṣe á;
Kún un mó sọmọ ria;
Kúùlu Ùpinṣà rójú,
Kí i ráyè;
Ọdún Ọ̀pá ti kò,
Ọdún ọbìnrin dì ti jọ ò.
Kú o yaa bá a pé;
Kú o bá a ṣọdún í;
Ká a yọ́ọ̀ ṣé yọrí;
Kẹ́ẹbọ Akápinṣà fín;
Kéètìtù Ìrẹṣí gbà;
Kí kete ria ṣọdún i láṣeyè ò
(Olódùmarè, ọba tó ba lórí gbogbo ayé,
A ké pè ọ
Kí o dákun dábọ̀
Jẹ́ kí ọdún Ọ̀pá wa kò láyọ̀ o
Kí o ṣe àtìlẹ́yìn fún Èyé Mọ̀é
Kí aboyún ilé bí wẹ́rẹ́;
Kí àgàn ki ọwọ́ àlà bọ osùn,
Kí ó wo ọmọ yè;
Kí ọdún Ọ̀pá múre wọ inú ìlú;
Kí aburú má ṣe wá;
Kí aburú má ṣe ọmọ wa;
Kí ìlú Ìpinṣà rójú,
Kí ó ráyè;
Ọdún Ọ̀pá ti kò,
Ọdún obìnrin tún ti jọ ò,
Kí o wá bá wa pé;
Kí o bá wa ṣọdún yìí;
Kí a lè ṣe é yọrí.
Kí ẹbọ Akápinṣà fín;
Kí ètùtù Ìrẹṣí gbà;
Kí gbogbo wa ṣe ọdún yìí ní àṣeyè o)

Ìwúre ọjọ́ kẹsàn án sí ọjọ́ ọdún Ọ̀pá yìí ṣe pàtàkì púpọ̀ nítorí pé òhun ni ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ fún ọdún Ọ̀pá. Bí ìwúre ìbẹ̀rẹ̀ yìí ṣe wà fún tonílé tàlejò, bákan náà ni ó wà láti ké pe Èyé Mọ̀é pé ọdún ti kò, àwọn ará ìlú Ìpinṣà sì fẹ́ kí ó dara pọ̀ mọ́ wọn, kí ọdún ba lè yọrí sí ìbùkún jìn-gbìn-nì fún gbogbo wọn, pàápàá jù lọ àwọn obìnrin tí wọ́n fẹ́ ire ọmọ. Ọladiran (2020:61) ṣe àlàyé pé “àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ ní ìgbẹ́kẹ̀lé àti ìgbàgbọ́ kikún nínú ètùtù àti ẹbọ rírú sí àwọn òrìṣà . . . láti wá ojúrere wọn, kí wọn ó lè bá wọn pẹ̀rọ̀ sí ìlú, kí ohun gbogbo le tùbàtùṣẹ fún àwọn olùgbé àwùjọ.” Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ọladiran, ìgbẹ́kẹ̀lé kíkún tí àwọn ọlọ́dún

ìbílẹ̀ Ọ̀pá ní nínú ètùtù ṣíṣe àti ẹbọ rírú ni okùnfà bí Akápinṣà ṣe ń pa ẹran láti ṣe ètùtù oríkádún ní ìbẹ̀rẹ̀ ọdún ìbílẹ̀ Ọ̀pá. Yàtọ̀ fún èyí, Akápinṣà a máa ṣe ètò pẹ̀lú àwọn obìnrin tí yóò bá a dáná fún gbogbo ará ìlú Ìpinṣà ní ọjọ́ kejì ọdún Ọ̀pá, ìwà ọ̀làwọ́ Kábíyèsí yìí a máa mú ìwúrí bá tonílé-tàlejò, a sì máa mú kí ìbáṣepọ̀ tímọ́tímọ́ tí ó wà láàrin àwọn olùgbé ìlú túbọ̀ lágbára sí i.

Ọdún Ìjẹ̀ṣu ni ó gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ ọdún Ọ̀pá. Àṣà ṣíṣe ọdún Ìjẹ̀ṣù ní ọjọ́ tí ó ṣáajú ọdún Ọ̀pá yìí ni àwọn ará Ìpinṣà mọ̀ sí ìdáṣu Akápinṣà pẹ̀lú Ọ̀pá. Láti ìgbà tí iṣu tuntun bá ti jáde, wọn kò gbọdọ̀ mú iṣu wá sí ààfin Akápinṣà títí di ìgbà tí yóò ṣe ọdún Ìjẹ̀ṣu pẹ̀lú ọdún Ọ̀pá. Pàtàkì ọdún Ìjẹ̀ṣu yìí ni pé kábíyèsí gbọ́dọ̀ ṣe ọdún náà kí ó tó bẹ̀rẹ̀ sí í jẹ iṣu. Ní ilẹ̀ Yorùbá, iyán ni oúnjẹ ìbílẹ̀ tí ó gbajúmọ̀ jù lọ níbi àwọn ayẹyẹ. Ayẹyẹ ọdún ìbílẹ̀ náa kò gbẹ́yìn. Nítorí náà, kí Akápinṣà ba lè jẹ iṣu tàbí kí ó gbádùn iyán pẹ̀lú àwọn ẹbí, ará, ọ̀rẹ́ àti àwọn àlejò tí ó wá bá a ṣe ọdún Ọ̀pá, ó gbọ́dọ̀ ṣe ọdún Ìjẹ̀ṣu ṣáájú ọdún náà.

**Ṣíṣe Ọdún Ọ̀pá ní Ìlú Osí**

Ọdún Ọ̀pá jẹ́ ọdún ìbílẹ̀ tí ó ti wà láti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́yìn. Ọjọ́ kan náà ni Osí àti Ìpinṣà gbọ́dọ̀ ṣe ọdún Ọ̀pá ní ìlú olúkúlùkù wọn ní ìbámu pẹ̀lú àṣẹ tí Èyé Mọ̀é pa fún àwọn ará Ìpinṣà. Èyí ló fà á tí Akápinṣà kò fi ní àǹfààní láti bá Ìrẹ̀ṣí ṣe ọdún Ọ̀pá mọ́. Ìrẹ̀ṣí náà kò sì ní àǹfààní láti bá Akápinṣà ṣe ọdún Ọ̀pá. Ní àárín yìí, ó ṣe pàtàkì láti mẹ́nu bà á pé gbogbo ire tí wọ́n bá wù ní ìwájú òrìṣà Akin ní ìlú Osí, tó fi mọ́ ètùtù tí wọ́n bá ṣe ni ó gbọ́dọ̀ dá lórí ìlú méjèèjì nítorí pé ọmọ ìyá kì í yà.

Ní òwúrọ̀ ọjọ́ ọdún Ọ̀pá, Olótùú Àjíóre àti àwọn ará ìlú Osí tí wọ́n jùmọ̀ yọ ayọ̀ ọdún káàkiri ìlú yóò lọ sí ojú Akin láti ṣe ètùtù ráńpé. Olótùú Àjíore yóò pa obì, yóò sì dà á. Àwọn tí wọ́n wà pẹ̀lú rẹ̀ yóò jẹ́rìí sí i pé obì náà yàn. Lẹ́yìn náà yóò bu ẹmu sí inú igbá, yóò sì máa wúre pé:

| | |
|---|---|
| Akinlúùsẹ̀ ọ̀rìṣà fifun | Akinlúùsẹ̀, òrìṣà funfun |
| Kè e lúlé àba mi, | Tí ó wà ní ilé bàbá mi, |
| Ọdún Ọ̀pá ti kò baí ò | Ọdún Ọ̀pá ti kò báyìí o, |
| Ya bá a pé | Wá bá wa pé, |
| Kete ẹbọ kà a rú | Gbogbo ẹbọ tí a ó rú |
| Lásìkò ọdún i, | Ní àsìkò ọdún yìí, |
| Kú o ju fín | Kí o jẹ́ kí ó fín |
| Kú o jétìtù ria gbà | Kí o jẹ́ kí ètùtù wa gbà |
| Lásìkò àbá ria Okùnatọ́ | Ní àsìkò bàbá wa, Okùnatọ́, |
| Káyé ria rójú | Kí ayé wa rójú |
| Kúùlú tòrò bóomi | Kí ìlú tòrò bí omi |
| Afọ̀úrọ̀ pọn, | Tí a fi òwúrọ̀ pọn, |
| Kí i mó sógun | Kí ó má ṣe sí ogun, |
| Kí i mó sọtẹ̀ | Kí ó má ṣe sí ọ̀tẹ̀ |
| Atẹ́gùn ire kè e fẹ́ líbe í | Atẹ́gùn ire tí ó ń fẹ́ níbí yìí |
| Kí i dì fẹ́ lÚpinṣà | Kí ó tún fẹ́ ní Ìpinṣà |

| | |
|---|---|
| Kú o bÁkápinṣà ṣùlú rẹ̀ | Kí o bá Akápinṣà ṣe ìlú rẹ̀ |
| Kí kete ria yọ̀ọ̀ a ṣọpẹ́ kò ọ́ | Kí gbogbo wa lè máa dúpẹ́ lọ́wọ́ rẹ |
| Kọ̀ọdún Ọ̀pá ria mọ́pọ̀ ire | Kí ọdún Ọ̀pá wa mú ọ̀pọ̀ ire |
| Yí họ̀lú méjèèjì | Wọ inú ìlú méjèèjì |
| Àsẹ kete ùre kà á wú líbe í | Àṣẹ gbogbo ìre tí a wú níbí yìí |
| Lónìí, dọ́ọ́ rẹ ò, Olódùmọrè | Lónìí, di ọwọ́ rẹ ò, Olódùmarè |

Nínú ìwúre yìí, Olótùú Àjíóre ṣojú àwọn ará ìlú Osí àti ti Ìpinṣà láti késí Akinlúùsẹ̀ pé kí ó darapọ̀ mọ́ wọn kí ohun gbogbo ba lè rí bí wọ́n ṣe ń fẹ́. Umejei (2023:1) ṣe àlayé pé "*in many African societies, especially in Nigeria, cultural festivals are often conceptualized as a medium through which humans communicate with deities*." (Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwùjọ ní ilẹ̀ Áfíríkà, pàápàá jù lọ ní Nàìjíríà, àwọn ọdún ìbílẹ̀ ni a sàbá máa ń gbé kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tí à ń gbà mú kí ìbánisọ̀rọ̀ wáyé láàárín ènìyàn àti àwọn òrìṣà). Lẹ́yìn ìwúre ní ojú Akinlúùsẹ̀, Olótùú Àjíóre àti àwọn ènìyàn tí wọ́n jọ jó káàkiri ní alẹ́ àìsùn ọdún yóò lọ sí ààfin kábíyèsí láti júbà ọba wọn. Olótùú Àjíóre ni yóò ṣojú àwọn tí wọ́n lọ sí ààfin nínú ìbà jíjú. Yóò máa sọ pé:

| | |
|---|---|
| Ojú ko mọ́ba ria lónìí, | Ojú tí ó mọ́ ọba wa lónìí, |
| Ojúmọ́ ire ni. | Ojúmọ́ ire ni. |
| Ojú ko mọ́rẹṣí lónìí, | Ojú tí ó mọ́ Ìrẹṣí lónìí, |
| Ojúmọ́ ayọ̀ ni. | Ojúmọ́ ayọ̀ ni. |
| Àbá, wo ti ṣọdún èí ná, | Bàbá, o ti ṣe ọdún èyí ná, |
| Wàa dì ṣẹ̀rẹ̀mírìn. | O tún máa ṣe òmíràn. |
| Òde àrìsùn la a ti í bò, | Òde àìsùn ni a ti ń bọ̀, |
| A rì fọ̀ ká a fọ̀ ọ́ sí ọ fọ́ | A ní kí a sọ fún ọ pé |
| A ti tòde àrìsùn dé. | A ti dé láti òde àìsùn. |
| A dì ti ṣẹ̀tìtù kòlú lójú Akin | A sì ti ṣe ètùtù fún ìlú ní ojú Akin |
| Lúbámu pẹ̀lú àṣà àtùṣe ria | Gẹ́gẹ́ bí àṣà àti ìṣe wa |
| Líjọ́ ọdún Ọ̀pá. | Ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pá. |
| Àbá wo kú ọdún, | Bàbá, o kú ọdún, |
| Wo kú ùyèdún, | O kú ìyèdún, |
| Ẹ̀mi kete ria á ṣùmọ́dún, | Ẹ̀mí gbogbo wa yóò ṣe àmọ́dún, |
| Sọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún láyé. | Yóò sì ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún láyé. |

Kábíyèsí yóò kí wọn káàbọ̀, yóò sì wúre ọdún fún Olótùú Àjíóre, àwọn ènìyàn tí wọ́n jọ wá sí ààfin àti gbogbo ìlú pátá:

| | |
|---|---|
| In káàbọ̀, a kú ọdún, | Ẹ kú àbọ̀, a kú ọdún, |

| | |
|---|---|
| A kú ùyèdún. | A kú ìyèdún. |
| Ẹ̀mí ria ko rọ́dún èí | Ẹmi wa tí ó rí ọdún èyí |
| Lá a dì sẹ̀rẹ̀mírìn | Ni yóò ṣe òmíràn |
| Á ra a ṣọdún ùbànújẹ́ | A kò níí ṣe ọdún ìbànújẹ́ |
| Ọdún Ọ̀pá kà á ṣe lónìí, | Ọdún Ọ̀pá tí a ṣe lónìí, |
| Á mítẹ̀síwájú bálú ria | Yóò mú kí ìtẹ̀síwájú bá ìlú wa |
| Á ra a dèrò èyìn | A kò níí di èrò ẹ̀yìn |
| Kete ìnọn ọmọ ria kè e lídálẹ̀ | Gbogbo àwọn ọmọ wa tí ó wà ní ìdálẹ̀ |
| Ra a gbé sájò | Kò níí gbé sí àjò |
| Lágbára Olódùmọrè, ọdún Ọ̀pá í | Ní agbára Olódùmarè, ọdún Ọ̀pá yìí |
| Á san kete ria ò. | Yóò san gbogbo wa ò |

Lẹ́yìn ìwúre, kábíyèsí yóò fún Olótùú Àjíóre àti àwọn ènìyàn tí wọ́n bá a lọ sí ààfin ní ẹ̀bùn ọdún. Wọn a fi ìmọríri hàn fún kábíyèsí, wọn a sì tẹ̀ síwájú nínú ijó jíjó àti orin kíkọ.

Lọ́tẹ̀ yìí, iwájú ilé Olótùú Àjíore ni àwọn ènìyàn náà yóò péjú sí. Olótùú Àjíore tí ó lé iwájú wọn, yóò wọ inú ilé lọ láti múra ní ìbámu pẹ̀lú àyè rẹ̀ àti ipò tí ó dìmú gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá. Bí ó bá ti wọ aṣọ tí ó jọjú tán, yóò fi ìró ṣe ìlàpà sí ọrùn. Nígbà tí ó bá padà jáde sí àwọn ènìyàn tí wọ́n ń dúró dè é ní ojúde rẹ̀, àwọn ènìyàn náà yóò hó ìhó ayọ̀, wọn a sì bẹ̀rẹ̀ sí kọ orin pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: Olótùú Àjíore ò, | Lílé: Olótùú Àjíore ò, |
| Ègbe: Ògbìgbò ri fò, inú ń bẹ́yẹ oko | Ègbè: Ògbìgbò padà fò, inú ń bí ẹyẹ oko |
| Lílé: Olótùú Àjíore ò, | Lílé: Olótùú Àjíore ò, |
| Ègbè: Ògbìgbò rí fò, inú ń bẹ́yẹ oko | Ègbè: Ògbìgbò padà fò, inú ń bí ẹyẹ oko |

Olótùú Àjíóre yóò mọ rírì àwọn ènìyàn náà, yóò sì wúre ọdún fún wọn pé:

| | |
|---|---|
| Kete ria kà a líbe í | Gbogbo àwa tí ó wà ní ibí yìí |
| Àti kete ùlú lápapọ̀ | Àti gbogbo ìlú ní àpapọ̀, |
| A ra a mọ́dún i ṣàṣemọ ò | A kò nì fi ọdún yìí ṣe àṣemọ ò |
| Ugbá ulé ria ra a fọ́ | Igbá ilé wa kò níí fọ́ |
| Àò ulé ria ra a fàya | Àwo ilé wa kò níí fàya |
| Àṣeyè lí kete ria á ṣọdún i ò | Àṣeyè ni gbogbo wa yóò ṣe ọdún yìí o |

Lẹ́yìn ìwúre, Olótùú Àjíóre yóò ṣe àwọn ènìyàn náà ní àlejò pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ obì, akèrègbè ẹmu àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ awùsá. Àwọn ènìyàn náà yóò mu ẹmu, wọn yóò sì pín obì àti awùsá láàrin ara wọn. Lẹ́yìn náà, olúkúlùkù yóò gba ilé rẹ̀ lọ láti múra.

Nígbà tí yóò bá fi di ọwọ́ aago méjìlá ní ọdún Ọ̀pá yóò wà bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Ṣáájú àkókò yìí, àwọn ènìyàn ìlú yóò máa gbọ́ àwọn orin ìgbàlódé bíi fújì, juju, ṣákàrà àti bẹ́ẹ̀

bẹ̀ẹ̀ lọ láti dáwọ̀ọ́ ìdùnnú. Àmọ́ bí ó bá ti di ọwọ́ aago méjìlá tí à ń sọ yìí, àwọn ènìyàn yóò pa àwọn orin ìgbàlódé tí wọ́n ń gbọ́ tì, tí orin ìbílẹ̀ yóò wá bẹ̀rẹ̀, ìyẹn àwọn orin tí ó rọ̀ mọ́ ọdún Ọ̀pá.

Àwọn ọlọ́dún ìbílẹ̀ Ọ̀pá a máa dáṣà báyìí pé: "Ùpọ̀n líí yanni rẹ̀." Ìtumọ̀ ìpèdè yìí ni pé ẹni tí yóò bá jẹ pàṣán, pàápàá èyí tí wọ́n ń pè ní "ọ̀pá ojú Akin" imọlẹ̀ Akin fúnraa rẹ̀ ni yóò mú un. Nígbà tí èyí bá sẹlẹ̀, ẹni náà yóò fínnú fíndọ̀ bọ́ sítá láti jẹ pàṣán. Yóò bọ́ aṣọ sílẹ̀, ìyẹn ni wọ́n ń pè ní "kí ènìyàn jẹ ọ̀pá ní gidigbi." Tí ó bá jẹ́ ọkùnrin ni ó fẹ́ jẹ pàṣán yìí, kò níí wọ aṣọ bíi ṣẹ́ẹ̀tì tàbí bùbá, ṣòkòtò nìkan ni yóò wà ní ìdí rẹ̀. Bí ó bá sì jẹ́ obìnrin ni ó fẹ́ jẹ pàṣán ní gidigbi, yóò sán aṣọ mọ́ àyà, yóò sì ró ìró mọ́ ìdí. Bí ó bá sì jẹ́ bùbá béńbé àti síkẹ́ẹ̀tì tàbí ṣòkòtò ni ó wọ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀dọ́bìnrin ti ń múra ní òde òní, yóò ká bùbá béńbé náà sí òkè láti jẹ pàṣán. Gẹ́gẹ́ bí àwọn àwòrán ìsàlẹ̀ ṣe fi hàn:



**Ọ̀dọ́bìnrin tó ká ẹ̀wù sókè ń jẹ pàṣán ní ìlú Osí**



**Ọ̀dọ́kùnrin ń jẹ pàṣán láìwọṣọ ní ìlú Osí**

Ọ̀pá jíjà ní àsìkò ọdún Ọ̀pá ní ètò púpọ̀. Àwọn ènìyàn kì í dédé na ara ní àsìkò ọdún náà, ẹni tí ó bá fẹ́ láti jẹ pàṣán ni yóò ká ọwọ́ méjèèjì sókè láti jẹ́ kí àwọn ènìyan mọ̀ pé wọ́n lè na òun ní pàṣán.

Olókorùn ni àgbà àwọn olóyè mẹ́ta tí wọ́n jọ wà ní ìgbọ́nnu ọdún Ọ̀pá. Òun gan an ni ó ni ọ̀pá jíjà. Ní èdè mìíràn, Olókorùn ni alábòójútò ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń wáyé níbi tí ọ̀pá ojú akin wà. Ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pá, Olókorùn ló ń gbé ẹmu ojú Akin tí a tún mọ̀ sí ẹmu ojo.

Ṣáájú kí Ìrẹṣí tó ṣí ọ̀pá jíjà ní ibi tí ojú Akin wà fún gbogbo ìlú nípa nína ọmọkùnrin rẹ̀ ní pàṣán níbẹ̀, àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá yóò ti ja ọ̀pá tiwọn níbẹ̀. Olókorùn yóò dúró sí ojú Akin, yóò gbé akèrègbè ẹmu sí iwájú rẹ̀, yóò sì kó pàṣán dání. Ìpèdè tí yóò máa jáde láti ẹnu rẹ̀ ní àsìkò yìí ni: “àjà òkè ya gbà” (àjà òkè wá gbà). Ìpèdè yìí wà láti késí àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá ẹlẹgbẹ́ rẹ̀: Elégirì, Olórógbè, Olótùú Àjíóre àti àwọn Ègirì (àwọn ọ̀dọ́kùnrin) tí ó wà ní pèpé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn láti súré wá ja ọ̀pá ojú akin.

Ẹ̀ẹ̀mẹta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Olókorùn yóò pe èdè tí a yọ lò lókè yìí, kí ó tó pè é ní ìgbà kẹta, àwọn tí ó ń pè yóò ti péjọ sí iwájú rẹ̀. Wọn yóò sì ká ọwọ́ méjèèjì sí òkè láti jẹ pàṣán. Lẹ́yìn tí Olókorùn bá na àwọn olóyè ọdún bíi tirẹ̀ ní pàṣán tán, àwọn olóyè náà yóò na àwọn Ègirì (ọ̀dọ́) tí ó wà ní abẹ́ àbójútó ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. Àwọn Ègirì náà yóò ja ọ̀pá tiwọn níbẹ̀ nípa nína ara wọn ní pàṣán. Àwòrán Ojú-Akin àti ọ̀pá rẹ̀ nìyí ní ìsàlẹ̀ yìí:




**Ojú Akin àti Ọ̀pá Ojú Akin**

Síwájú sí i, wọn kì í na àwọn àgbàlagbà ní àsìkò ọdún náà. Àmọ́, àgbàlagbà a máa na ọmọdé tí ó bá ká ọwọ́ sí òkè láti fi hàn pé òun fẹ́ jẹ pàṣán. Kódà, bí àgbàlagbà bá ká ọwọ́ sí òkè láti jẹ́ kì àwọn ènìyàn mọ̀ pé wọ́n lè na òun, kò sí ẹni tí yóò nà án. Àṣà yìí ṣe àfihàn àṣà ìbọ̀wọ̀ fún àgbà ní àárín àwọn Yorùbá. Tọkùnrin tobìnrin ló ń jẹ pàṣán ní àsìkò ọdún Ọ̀pá ní ìlú Osí. Àmọ́, àkíyèsí ni pé ìyàtọ̀ wà láàrin bí wọ́n ṣe ń na ọkùnrin àti obìnrin ní pàṣán. Bí ọkùnrin bá ká ọwọ́ sí òkè ní ẹ̀ẹ̀mẹwàá tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, wọn yóò máa nà án. Àmọ́, bí wọ́n bá ti na obìnrin kan ní ìgbà méjì mẹ́ta, tí obìnrin náà ṣì pàpà ń ká ọwọ́ sókè, wọn kò níí nà án mọ́.

Olókorùn ni alábòójútó ìṣẹ̀lẹ̀ tí yóò wáyé ní ibi tí wọn yóò ti ja ọ̀pá ojú Akin. Òun ni yóò gbé ẹmu ojo síbẹ̀. Òun ni yóò sì bù ú fún ọmọkùnrin ọba tí yóò jẹ́ ẹni àkọ́kọ́ láti jẹ ọ̀pa ojú Akin àti àwọn mìíràn tí yóò jẹ pàṣán lẹ́yìn rẹ̀.

Ìdìpọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀pá kan wà tí wọ́n fi màrìwò wọ̀ láṣọ láti òkè dé ilẹ̀. Ohùn akin àti Olókunrùn nìkan ni ó ní àṣẹ láti gbé e. Ọ̀pá Ọlọ́finlẹ́yọ̀ ni wọ́n ń pè é, kì í ṣe ẹnikẹ́ni ni ó lè gbé e. Ní ìgbà tí ọdún bá ń lọ lọ́wọ́, tí àwọn ènìyàn ń ja ọ̀pá tí wọ́n sì ń jó káàkiri, Ohùn akin tàbí Olókunrùn ni yóò máa gbé ọ̀pá náà jó káàkiri. Ọ̀pá Ọlọ́finlẹ́yọ̀ gbọ́dọ̀ wà ní ìdí ojú akin nígbà tí wọ́n bá fẹ́ ja ọ̀pá níbẹ̀. Ìdí pàtàkì tí ó fi gbọ́dọ̀ wà níbẹ̀ ni pé ìránṣẹ́ ni ó jẹ́ fún Akinlúùsẹ̀.



**Olókorùn, Ohùn Akin, ọ̀pá ọlọ́finlẹ́yọ̀ àti ẹmu ojo**

Ẹmu ojo ni àwọn ará Osí ń pe ẹmu inú igbá tí àwọn tí ó bá fẹ́ fi ìgboyà jẹ pàṣán ní ìdí ọ̀pá ojú akin máa ń gbé dání. Ẹni náà yóò fi ọwọ́ ọ̀tún di igbá mú, yóò sì na ọwọ́ òsì sí òkè. Gbàrà tí ó bá ti bẹ̀rẹ̀ sí mu ẹmu inú igbá ọwọ́ rẹ̀ ni yóò ti máa fi ara gba pàṣán lọ́tùn-ún lósì. Ó di ìgbà tí ó bá mu ẹmu náà tán tí ó sì ka ọwọ́ rẹ̀ òsì wálẹ̀ kí wọn tó síwọ́ nínà án. Ìdí tí irúfẹ́ àwọn ènìyàn wọ̀nyí fi nílò ìgboyà ni pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ pàṣán ni ó máa ń pàdé sí ara wọn lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo.

Ẹni tí kò bá tíì jẹ pàṣán kankan láti ìgbà tí ọdún Ọ̀pá ti bẹ̀rẹ̀ ni ó máa ń jẹ pàṣán ní ibi tí ọ̀pá ojú akin wà. Ọmọkùnrin ọba ni ó gbọ́dọ̀ ṣí pàṣán jíjẹ nídìí ọ̀pá ojú akin, ẹ̀gbẹ́ ibi tí ọ̀pá yìí bá wà ni kábíyèsí yóò ti mú ẹyọ ọ̀pá kan ṣoṣo, yóò sì fi na ọmọkùnrin rẹ̀ tagbára tagbára lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo. Àwọn ènìyàn yóò hó ìhó ayọ̀. Ìrẹ̀ṣí yóò sì fi ohun ọ̀ṣọ́ kọ́ ọmọ ọba lọ́rùn láti ṣe àfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí aláṣeyọrí.



**Kábíyèsí ń fi ìlẹ̀kẹ̀ sí ọmọkùnrin rẹ̀ tí ó kọ́kọ́ jẹ ọ̀pá ojú Akin ní ọ̀sán ọjọ́ ọdún lọ́rùn**

Ẹni tí ó bá fẹ́ jẹ pàṣán níbi tí ọ̀pá ojú akin wà lẹ́yìn tí kábíyèsí bá ti ṣí jíja ọ̀pá níbẹ̀, yóò múra tán láti jẹ pàṣán láti ọwọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé ṣáájú. Nígbà tí nínà yìí bá ti pọ̀ jù, àwọn àgbàlagbà tó wà ní ìkàlẹ̀ yóò dá àwọn ènìyàn lẹ́kun, wọn yóò ní kí ẹnikẹ́ni tí ó bá kọ etí ikún sí ìkìlọ̀ yìí jọ̀wọ́ pàṣán ọwọ́ rẹ̀ fún ègirì yòówù tí ó bá wà ní itòsí, wọn kò sì gbọdọ̀ rí pàṣán ní ọwọ́ rẹ̀ mọ́ títí tí ọdún Ọ̀pá yóò fi wá sí ìparí. Irúfẹ́ ìbáwí yìí wà láti gbin pàtàkì ṣíṣe ìgbọràn sí àṣẹ tí àwọn àgbàlagbà pa fún àwọn ọ̀dọ́ àti àwọn ọmọdé lọ́kàn. Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe ń sọ bọ̀, bí ẹni tí ó jẹ pàṣán níbi ọ̀pá ojú akin, lẹ́yìn ọmọ ọba bá ti kúrò níbẹ̀. Ẹlòmíràn yóò tún bọ́ síta láti jẹ pàṣán níbi ọ̀pá ojú akin. Àwọn tí yóò jẹ pàṣán níbi tí ọ̀pá ojú akin wà lè jẹ́ márùn-ún sí mẹ́fà.

**Ṣíṣe Ọdún Ọ̀pá ní Ìlú Ìpinṣà**

Bí ó bá ti di ọwọ́ ìyálẹ̀ta sí ọwọ́ aago méjìlá ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pa gan-an, àwọn ará abúlé tí wọ́n jó ijó àjómọ́jú pẹ̀lú àwọn ènìyàn Ìpinṣà ní alẹ́ tí ó ṣáájú ọjọ́ ọdún yóò bẹ̀rẹ̀ sí dé sí ìlú náà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, ẹ̀jẹ̀ẹ̀jì. Alẹ́ àìsùn ọdún yìí ni wọ́n ń pè ní alẹ́ àjómọ́jú. Nígbà tí aago bá ń lọ sí ọwọ́ aago méjì, ọdún Ọ̀pá yóò bẹ̀rẹ̀. Àwọn ènìyàn lọ́kùnrin, lóbìnrin, ọmọdé àti àgbà yóò péjú pésẹ̀ sí ààfin Akápinṣà. Àwọn obìnrin yóò máa pohùn, wọn a sì máa dá ọ̀kan-ò-jọ̀kan orin. Lára àwọn orin tí wọ́n máa ń kọ lọ báyìí pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ jáde ò, | Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ jáde ò, |
| Ègbè: Ìhòrògún jáde umọlẹ̀. | Ègbè: Ìhòrògún jáde imọlẹ̀. |
| Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ jáde ò, | Lílé: Ẹlẹ́gbẹ́ jáde ò, |
| Ègbè: Ìhòrògún jáde umọlẹ̀. | Ègbè: Ìhòrògún jáde imọlẹ̀. |

Orin yìí ni àwọn obìnrin máa ń kọ láti ké sí àwọn ènìyàn lọ́kùnrin lóbìnrin pé ọdún ti bẹ̀rẹ̀, kí wọ́n tú yáyá jáde láti kó ipa tiwọn. Wọn a tún máa kọ orin pé:

| | |
|---|---|
| Lílé: Éè jí mi jíjọ̀pá, | Lílé: Kò jẹ́ kí n lè jẹ ọ̀pá (pàṣán) |
| Ègbè: Àọ̀ mi ò, èrè pèrèmọ̀. | Ègbè: Àwọ̀ mi ò, ohun ẹlẹgẹ́ tí ó rẹwà |
| Lílé: Éè jí mi jíjọ̀pá, | Lílé: Kò jẹ́ kí n lè jẹ ọ̀pá (pàṣán) |
| Ègbè: Àọ̀ mi ò, èrè pèrèmọ̀. | Ègbè: Àwọ̀ mi ò, ohun ẹlẹgẹ́ tí ó rẹwà |

Orin yìí ni àwọn obìnrin máa ń kọ láti ṣe àpọ́nlé fún ara wọn. Wọn a máa lo orin náà láti tọ́ka sí i pé àwọ̀ àwọn lẹ́wà, àti pé ìdí nìyí tí àwọn kò fi lè jẹ pàṣán, nítorí pé wọn kò fẹ́ kí àwọ̀ wọn bàjẹ́. Bí àwọn obìnrin ìlú Ìpinṣà ṣe mọyì ara wọn yìí, bákan náà ni àwọn ọkùnrin ìlú Ìpinṣà mọyì, tí wọ́n sì mọ rírì àwọn obìnrin wọn púpọ̀. Ojo (2021:111) sọ pé "*women should be respected, celebrated and placated in order to win their favours.*" (ìbọ̀wọ̀-fúnni, ìṣẹ̀yẹ-fúnni àti mímú ọkàn-ẹni-wálẹ̀ tọ́ sí àwọn obìnrin bí a bá fẹ́ rí ojúrere wọn). Ní ìbámu pẹ̀lú èrò onímọ̀ yìí, ẹ̀rí fi hàn pé àlááfíà jọba láàárín takọ-tabo ìlú Ìpinṣà nítorì ìhà àpọ́nlé tí àwọn ọkùnrin kọ sí àwọn obìnrin wọn. Àsìkò ọdún ìbílẹ̀ Ọ̀pa ni ẹ̀rí ìbáṣepọ̀ ọlọ́rẹ̀ẹ́-sọ́rẹ̀ẹ́ tó wà láàárín àwọn olùgbé ìlú Ìpinṣà máa ń hànde jù lọ. Ossai-Uloku àti Anyawu (2024:185) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé "*festival strenthens the bond of love and spirit of togetherness existing among people in the community*," (ọdún ìbílẹ̀ a máa mú kí okùn ìfẹ́ àti ẹ̀mí àjọwà tó wà láàárín àwọn ènìyàn àwùjọ túbọ̀ yi sí i).

Bí àwọn ọkùnrin bá ṣe ń jẹ pàṣán, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin yóò máa kọ orin. Wọn kì í na obìnrin ní pàṣán ní ìlú Ìpinṣà, ìdí ni pé obìnrin gan-an ni ó ni ọdún náà. Àwọn ni wọ́n sì ń fi ọdún Ọ̀pá bu ọlá fún. Àwọn ọkùnrin a máa na ọkùnrin; àwọn obìnrin náà a máa na ọkùnrin. Bí obìnrin tí ó na ọkùnrin bá fẹ́, ó lè ta ọkùnrin tí ó nà ní ọrẹ owó, ó sì lè ṣe aláìṣe bẹ́ẹ̀.

Ní àsìkò ọdún Ọ̀pá, àwọn ìyá ọlọ́mọ a máa kó àwọn ọmọkùnrin kéékèèké síta láti nà wọ́n ní pàṣán. Wọn a máa ṣe èyí láti jẹ́ kí pàṣán jíjẹ mọ́ wọn lára láti ìgbà ọmọdé di ìgbà tí wọ́n bá di àgbàlagbà. Ojúṣe kábíyèsí àti àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ni láti ṣe ètùtù ráńpẹ́ ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pá. Oṣù kẹta ọdún ni wọn yóò ti gé igi, wọn a sì rí igi náà mọ́lẹ̀ sí ìtòsí ààfin kábíyèsí. Kí oṣù keje tí wọ́n ń ṣe ọdún Ọ̀pá tó kò, igi náà yóò ti yọ ewé lórí. Ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pá, wọn yóò ta màrìwò yí igi náà ká. Lára àwọn èròjà ìmúlò ní àkókò yìí ni abo adìyẹ, ọtí ìbílẹ̀ àti obì. Olókorùn ni yóò pa adìyẹ náà, tí yóò sì ta ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ sílẹ̀ nídìí igi tí wọ́n ta màrìwò yí ká yìí. Yorùbá gbàgbọ́ pé obì níí bi ikú àti àrùn dànù. Nítorí náà, obì àti ọtí ìbílẹ̀ ni wọn yóò fi wúre níbẹ̀. Kábíyèsí ni yóò kọ́kọ́ wúre:

| | |
|---|---|
| Olódùmọrè, ọba adẹ́dàá; | Olódùmarè, ọba adẹ́dàá; |
| Ọba aṣẹ̀dá; | Ọba Aṣẹ̀dá; |
| Èrèkò i èṣí, kà á ṣọdún, | Ìwòyí èṣí tí a ṣe ọdún, |
| A bẹ̀bẹ̀ fọ̀ kú o dá a sí tebí-tará | A bẹ̀bẹ̀ pé kí o dá wa sí tẹbí-tará, |
| Ká a dì yoò péjú ṣọdún. | Kí a tún le péjú ṣe ọdún |
| Wo gbóhùn ria, | Ó gbọ́ ohùn wa, |
| Ukú ù pa á; | Ikú kò pa wá; |
| Ukú ù pọmọ ria; | Ikú kò pa ọmọ wa; |
| Ukú ù palátìleyìn; | Ikú kò pa alátìlẹyìn |
| A júbà rẹ ò, Ọ̀gá Ògo . . . | A juba rẹ ò, Ọ̀gá Ògo . . . |

Gbogbo àsìkò tí kábíyèsí bá fi ń wúre ni àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá yóò máa sọ pé àṣẹ. Lẹ́yìn ìwúre kábíyèsí, Olórí Ìfà yóò wúre, bí Olórí Ìfà bá ṣe ń parí ìwúre rẹ̀, Olórógbè yóò hán an pọ́nkán, Olóòtú Àjíóre náà yóò wúre ọdún. Yorùbá a máa sọ pé, àìbá wọn sí níbẹ̀ ni àìbá wọn dá sí i. Sàò, ọ̀kan lára àwọn olóyè àgbà náà kò gbẹ́yìn nínú ṣíṣe ìwúre ọdún. Nígbà tí àwọn ará Ìpinṣà ń wúre, àkíyèsí ni pé àwọn kan lára wọn dárúkọ Jagunlóògbè, wọ́n sì ṣe àpèjúwe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí "Akọni líjọ́ kojú ogun le" ("Akọni ní ọjọ́ tí ojú ogun le"). Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé Òrìṣà Akin, tí àwọn ará Osí ń pè ní Akinlúùsẹ̀ ni àwọn ará Ìpinṣà ń pè ní Jagunlóògbè.

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, nínú ìwúre tí Sàò, tíí ṣe olóyè àgbà ṣe, ó gbẹnusọ fún àwọn ará Ìpinṣà láti késí Akinlúùsẹ̀ pé kí ó darapọ̀ mọ́ Èyé Mọ̀é, kí ó sì ṣe àtìlẹ́yìn fún un láti mú gbogbo àlá rere wọn wá sí ìmúṣẹ. Ìdí tí èyì fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé bí a bá perí ajá, a óò perí ìkòkò tí a fi sè é ni ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín Èyé Mọ̀é àti òrìṣà ilé bàbá rẹ̀ tí a mọ̀ sí Jagunlóògbè ní Ìpinṣà jẹ́. Lẹ́yìn tí kábíyèsí, àwọn olóyè ọdún àti olóyè àgbà bá ti wúre ọdún tán, àwọn olóyè ọdún yóò ja ọ̀pá ìba ní ìdí igi ìba. Ọ̀pá ìba ni ó dàbí ọ̀pá ojú akin tí wọ́n ń jà ní ìlú Osí. Ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ọ̀pá ìba àti ọ̀pá ojú akin ni pé ní ìlú Osí, ọmọkùnrin ọba yóò jẹ pàṣán láti ọwọ́ kábíyèsí. Àwọn ọ̀dọ́ lọ́kùnrin lóbìnrin yóò sì jẹ pàṣán, kì í ṣe láti ọwọ́ ẹni kan ṣoṣo ṣùgbọ́n láti ọwọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn. Àmọ́, ní Ìpinṣà, àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá ló ń ja ọ̀pá ìba. Ohun tí àwọn ará Osí mọ̀ sí ẹmu ojo tàbí ẹmu ojú Akin ni àwọn ará Ìpinṣà ń pè ní ẹmu agede tàbí ẹmu ìba.



**Wọ́n ń bu ẹmu ìba sínú igbá ní ìlú Ìpinṣà**

Àwọn èròjà tí wọ́n ń lò ní ibi ọ̀pá ìba ni pàṣán, igbá àti agede. Ó ní oríṣìí igbá tí wọ́n ń lò ní àsìkò yìí. Ẹ̀ẹ̀kan lọ́dún ni wọ́n ń lò ó. Ààfin Akápinṣà ni wọ́n ń tọ́jú igbá náà sí. Bí wọ́n bá ti lò ó ní ibi ọ̀pá ìba ní àsìkò ọdún Ọ̀pá tán, ó tún di àsìkò ọdún Ọ̀pá tí ó tẹ̀lé e kí wọ́n tó tún lò ó. Orí agede (agede jẹ́ abọ́ kékeré kan tàbí abọ́ kan tí wọ́n fi sí inú abọ́

mìíràn, amọ̀ ni wọ́n fi mọ ọ́n) ni wọ́n máa ń fi igbá náà lé. Ẹmu tí wọ́n bù sí inú igbá yìí ni wọ́n ń pè ní ẹmu agede tàbí ẹmu ìbá.

Bí àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá bá ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ sí ja ọ̀pá ìba, olórí Ìfà ni yóò kọ́kọ́ ṣí i. Olórí Ìfà yóò bu ẹmu sí inú igbá náà, àtẹ̀lé rẹ̀, Olórógbè yóò gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Bí Olórógbè bá ti ń mu ẹmu ìba báyìí, Olórí Ìfà yóò nà án ní pàṣán tó kira ní ẹ̀ẹ̀mẹta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, láàrin àsìkò tí ó ń fi ara gba pàṣán yìí, yóò ti mu ẹmu inú igbá ọwọ́ rẹ̀ tán. Olórógbè yóò bu ẹmu mìíràn sí inú igbá ọwọ́ rẹ̀, yóò sì gbé e fún Olótùú Àjíóre. Olótùú Àjíóre yóò gbà á, yóò sì bẹ̀rẹ̀ sí mu ẹmu náà, lẹ́yìn tí ó bá ti jẹ pàṣán láti ọwọ́ Olórógbè tán, òun náà yóò gbé ẹmu ìba fún Olókorùn, ẹ̀kẹrin wọn. Bí Olókorùn bá ṣe ń mu ẹmu náà báyìí, ni pàṣán yóò máa dún ní ara rẹ̀ láti ọwọ́ Olótùú Àjíóre. Báyìí ni jíja ọ̀pá ìba yóò ṣe wá sí ìparí. Ọ̀pá jíjà yóò sì bẹ̀rẹ̀ lákọ̀tun láàrin àwọn ọkùnrin ìlú. Ọ̀kan lára àwọn orin tí wọ́n máa ń kọ lọ báyìí pé:

Ọ̀pá Ùpinṣà ò, Ọ̀pá Ìpinṣà ò,
Òní la a para lígi, Òní la ó na ara wa ní pàṣán.
Òní ni. Òní ni.
Ọ̀pá Ùpinṣà ò, Ọ̀pá Ìpinṣà ò,
Òní la a para lígi, Òní la ó na ara wa ní pàṣán.
Òní ni. Òní ni.

Orin òkè yìí ni ó ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé òní lòní ń jẹ́ ẹni a bẹ̀ lọ́wẹ̀ ni ọ̀rọ̀ nípa ọ̀pá jíjà ní ọjọ́ ọdún Ọ̀pá tí wọ́n ń ṣe nì Ìpinṣà. Àwọn ọkùnrin ìlú náà mọ èyí, wọ́n sì fara mọ́ ọn. Bí àwọn ènìyàn kan ṣe ń jẹ, tí wọ́n sì ń mu, bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn mìíràn yóò máa kọ orin, tí wọn yóò sì máa jó, tí wọn yóò sì máa yọ ayọ̀ ọdún títí tí ọdún yóò fi tẹnu bodò.

**Títọ́ka sí Onírúurú Ìjọra àti Ìyàtọ̀ níbi Ọdún Ọ̀pá Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà**

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ló pa àwọn ọlọ́dún pọ̀ ní ìlú méjèèjì, síbẹ̀ a lè sọ àsọyán pé onírúurú nǹkan ló yà wọ́n sọ́tọ̀. Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe yán an lábẹ́ àṣamọ̀ iṣẹ́ yìí, kì í ṣe gbogbo ìgbòkègbodò tó ń wáyé ṣáájú, ní àsìkò àti lẹ́yìn ọdún Ọ̀pá ní ìlú Osí àti Ìpinṣà ló rí bákan náà. Ṣáájú ọdún méjèèjì, ìmúra tàbí ìgbáradì tó lówúra a máa wáyé. Irúfẹ́ ẹmu tí àwọn ará ìlú Osí ń pè ní ẹmu ojo tàbí ẹmu ojú-akin ni àwọn ará Ìpinṣà ń pè ní ẹmu ìba tàbí ẹmu agede. Ibi tí àmì ojú Akin wà ni wọ́n ti ń mu ẹmu ojo; ìdí igi ìba ni àwọn ti Ìpinṣà ti ń mu ẹmu agede. Ní ìlú méjèèjì, gbogbo ẹni tó bá fẹ́ mu ẹmu ojo tàbí ẹmu agede gbọ́dọ̀ ṣetán láti jẹ pàṣán, yálà láti ọwọ́ ẹnìkan ṣoṣo tàbí ọ̀pọ̀ èrò, gẹ́gẹ́ bí àwọn àlàyé tí ó ṣáájú ṣe fi hàn. Ní Osí, ọ̀gangan ibi tí Ojú-akin wà ni àwọn tí wọ́n bá fẹ́ fi ara gba ẹgba láti ọwọ́ ọ̀pọ̀ èrò ti ń mu ẹmu ojo.

Àwọn olóyè ọdún Ọ̀pá ló ń mu ẹmu ní ìdí igi ìba, àwọn ló sì ń ja Ọ̀pá níbẹ̀ ní ìlú Ìpinṣà. Ọ̀pá jíjà mú takọ-tabo mọ́ra ní ìlú Osí, àmọ́ ohun tí kò wọ̀ ni láti na obìnrin ní Ìpinṣà. Àwọn olóyè mẹ́rin ló wà ní ìgbọ́nnu ọdún Ọ̀pá ní ìlú méjèèjì, àwọn méjì tí wọ́n di ipò àkọ́kọ́ mú láàárín wọn ni orúkọ oyè wọn yàtọ̀ síra- Olókorùn ni a mọ àgbà àwọn olóyè wọ̀nyí sí ní Osí, Olórí-Ìfà ni à ń pe ti Ìpinṣà. Àwọn ìlú méjèèjì ló ń ṣe àìsùn ọdún pẹ̀lú ijó, ìlù àti ìdáwọ̀ọ́ ìdùnnú káàkiri ìlú. Nínú ojú àmúwayé àwọn ará ìlú méjèèjì, ìjúbà àti ìjábọ̀ ṣe pàtàkì ṣáájú àti lẹ́yìn àwọn ìgbésẹ̀ ṣíṣe kókó. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí àwọn ènìyàn bá fẹ́ jó káàkiri ìlú ní alẹ́ àìsùn ọdún, wọn a júbà, wọn a sì gba ìre lẹ́nu kábíyèsí kí wọn tó lọ. Nígbà tí wọ́n bá padà dé, wọn a jábọ̀, wọn a tún gba ìre. ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni ìre tàbí ìwúre máa ń wáyé ṣáájú, ní àkókò àti lẹ́yìn ọdún Ọ̀pá.

Raji (1991) sọ pé "ìwúre ni ire tí à ń wú láti inú ilẹ̀ àti ọkàn ẹni wá." Fákáyọ̀dé (2011) ṣe àlàyé pé àkànpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe náà, 'wúre,' túmọ̀ sí kí a wú ire, ohun dídára tàbí nǹkan tó ń mú inú ẹni dùn láti inú ilẹ̀. Àlàyé tí Raji (1991) ṣe ṣe ìtúpalẹ̀ ìwúre gẹ́gẹ́ bí ohun ṣíṣeyebíye tàbí ire tí ó wà nínú àgò tábí àhámọ́, tí a ń wú jáde ki ó ba le wúlò fúnni. Àkíyèsí pàtàkì tí kò ṣe é gbójú fò nínú àpilẹ̀kọ yìí ni pé jálẹ̀ gbogbo ìgbòkègbodò ọdún ni àwọn akópa ń wúre, nítorí wọ́n gbà pé òfúùtùfẹ́ẹ̀tẹ̀ ni gbogbo àníyàn tí wọ́n ń ṣe, yálà ní olùkúlùkù tàbí

lápapọ̀ yóò já sí, láìsí ìwúre. Yàtọ̀ fún èyí, àgbékalẹ̀ ìwúre wọ̀nyí tún ṣe àfihàn èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá pé kò sí ohunkóhun tí ènìyàn le ṣe ní àṣeyọrí láìsí àṣẹ àti àtìlẹ́yìn Olódùmarè. Bákan náà, ó tún ṣe àfihàn èrò ìran Yorùbá nípa níní ìbáṣepọ̀ tí kò ṣe tààrà pẹ̀lú Olódùmarè, ní ti pé wọn kì í jọ́sìn rẹ̀ lọ́nà tààrà, kàkà bẹ́ẹ̀ wọn a máà sìn ín nípasẹ̀ àwọn òrìṣà; ì bá à jẹ́ àtẹ̀wọ̀nrọ̀ tàbí akọni-dòrìṣà.

Nígbà tí àwọn akópa bá ń wúre ní àkókò ọdún, wọn a máa dárúkọ Èyé Mọ̀é àti Akinlúùsẹ̀ nínú ìwúre wọn láti fi hàn pé wọ́n ń wúre sí Olódùmarè nípasẹ̀ àwọn akọni-dòrìṣà wọ̀nyí. Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bà á ṣáájú, Akinlúùsẹ̀ tíí ṣe òrìṣà tí àwọn ará Osí fi ọdún Ọ̀pá sọrí ni àwọn ará Ìpinṣà ń pè ní Jagunlóògbè, nípa bẹ́ẹ̀ wọ́n ń fi ọ̀wọ̀ tirẹ̀ wọ̀ ọ́ gẹ́gẹ́ bí òrìṣà ilé Èyé Mọ̀é tíí ṣe akọni tiwọn. Ní Osí, àwọn ènìyàn a máa tẹ̀ síwájú láti ja Ọ̀pá ní ọjọ́ kejì ọdún, èyí ni wọ́n ń pè ní Adúpẹ́lorógbé, ṣugbọ́n ìkíni kú ọdún àná ni ó máa ń gbalégboko ní Ìpinṣà. Nígbà tí yóò bá fi di ọjọ́ kẹta ọdún, ìkíni kù ọdún àná yóò tẹ̀ síwájú ní Ìpinṣà. Àmọ́ ní Osí, orò ṣíṣe ní ń wáyé ní ọjọ́ kẹta ọdún Ọ̀pá, Ìmóróko ni àwọn ará Osí ń pe oro yìí. Ní ìlú méjèèjì, àwọn akópa a máa fi ìfẹ́ àrà-ọ̀tọ̀ hàn ní àsìkò ọdún, yàtọ̀ fún pé àjọjẹ, àjọmu a máa wáyé, wọn a máa ta ara wọn lọ́rẹ; wọn a sì máa fún ara wọn ní onírúurú ẹ̀bùn tó jọjú ní àsìkò ọdún

**Àgbálọgbábọ̀**

Àpilẹ̀kọ yìí jíròrò lórí onírúurú ìgbòkègbodò tó ń wáyé ṣáájú, ní àsìkò àti lẹ́yìn ọdún Ọ̀pá ní ìlú Osí àti Ìpinṣà. Àwọn ìgbòkègbodò wọ̀nyí ni ìmúrasílẹ̀ nípasẹ̀ àjọ ṣíṣe láti oṣù kẹta títí di oṣù keje tí ọdún Ọ̀pá yóò bẹ̀rẹ̀. Àkójọpọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ pàṣán fún ìlò ní àsìkò ọdún,

àkànṣe ọ̀pá jíjà ní ìlú méjèèjì; jíja ọ̀pá ojú akin ní Osí àti jíja ọ̀pá ìba ní Ìpinṣà. Ìlò ẹmu ojo níbi ọ̀pá ojú akin, ìlò ẹmu agede níbi ọ̀pá ìba, tó fi mọ́ onírúurú ìwúre láti ẹnu àwọn kábíyèsí áti àwọn olóyè ọdún ọ̀pá ní ìlú méjèèjì. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọdún ìbílẹ̀ kò lè ṣe àwọn akópa ní àǹfààní kankan bí onírúurú ìwúre tó yẹ kó wáyé ṣáájú, ní àsìkò àti lẹ́yìn ọdún kò bá wáyé. Iṣẹ́ ìwádìí yìí tọ́ka sí i pé àwọn ibi ṣíṣe kókó ni ìwúre ti máa ń wáyé ní àsìkò ọdún ìbílẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ọdún Ọ̀pá ní Osí àti Ìpinṣà, ìwúre a máa wáyé ní ààfin kábíyèsí, ojúbọ Akinlúùsẹ̀, ojú akin, abẹ́ igi ìba, iwájú òde àwọn olóyè ọ̀pá áti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìwádìí yìí ṣe àfihàn orin ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ewì alohùn tí ó máa ń ṣe àfihàn àṣà àti ìṣe Yorùbá.

Iṣẹ́ ìwádìí yìí sọ ojú abẹ níkòó pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọdún Ọ̀pá tí wọ́n ń ṣe ní Osí ló bí ọdún Ọ̀pá Ìpinṣà, síbẹ̀ kì í ṣe gbogbo ohun tí wọ́n ń ṣe ní Osí ni wọ́n ń ṣe ní Ìpinṣà, èyí túmọ̀ sí pé irúfẹ́ ìgbòkègbodò kan wà tí ó wọ̀ làti ṣe ní Osí, ṣùgbọ́n tí kò gbọdọ̀ ṣẹlẹ̀ ní Ìpinṣà. Ní Osí takọ-tabo ló ń ja ọ̀pá, irúfẹ́ ọ̀pá jíjà báyìí kò gbọdọ̀ ṣẹlẹ̀ ní Ìpinṣà, nítorí pé a kò gbọdọ̀ na obìnrin ní àsìkò ọdún Ọ̀pá Ìpinṣà. Orí èrò tí iṣẹ́ yìí gúnlẹ̀ sí ni pé bí a ṣe rí àwọn ìgbòkègbodò tó pa àwọn ọlọ́dún ìbílẹ̀ pọ̀, bákan náà ni a rí àwọn tó yà wọ́n sọ́tọ̀, síbẹ̀ a lè sọ àsọyán pé gbogbo ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ni ìwúre àti ètùtù ti gbọ́dọ̀ wáyé.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Adebua, B.O. and Sotunsa, M.E. (2018). “Dialectics and Structural Organization in Ẹ̀bìbì Festival Performances of the Ẹ̀pẹ́ People in Lagos State, Nigeria.” *Yorùbá Studies Review.* Vol.2, No. 2. Pp. 199-213.

Ararọba, T. O. (2019) “Àtúpalẹ̀ Ojú Àmúwayé Yorùbá nínú Lítíréṣọ̀ Ọdún Ọ̀pá ní Ìlú Osí àti Ìpinṣà ní Ìpínlẹ̀ Oǹdó.” (An Analysis of Yorùbá Worldview of the Orature of *Ọ̀pá* Festival in Oǹdó State). Unpublished Doctoral Thesis, submitted to the Department of Linguistics and African Languages, Ọbafẹmi Awolọwọ University, Ile-Ifẹ.

Fakayọde, F.F. (2011). *ÌWÚRE, Efficacious Prayer to OLÓDÙMARÈ, The Supreme Force*. Ibadan: Ejiodi Home of Tradition.

Ibrahim, D. (2020). “Women in Yorùbá and Hausa Folktales.” *Ifẹ Journal of Languages and Literatures*. Vol. 6, No 1. Pp. 102-118.

Logan, P.M. (2012). "On Culture: Matthew Arnold's Culture and Anarchy 1869" in Felluga, D.F. (ed.) Representation and Nineteenth Century History. New York. http: //www.branchcollective.org>ps_articles= . . . retrieved on March 18, 2025.

Obamwonyi, A.A. and Onyekuru, J.A. (2024). "The Role of Traditional African Festivals in the Sustenance of the Ecosystem: Ikenge Festival in Utagba-Uno, Southern Nigeria as a Paradigm." *Rupkatha Journal on Interdisciplinary Studies in Humanities*. Vol. 16, No 1. Pp. 1-17.

Ojo, I.F. (2021). "Representation of Women Power in Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Ritual Performance in Yorùbá Culture." *Yorùbá- The Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*.Vol. 10, No. 4. Pp. 101-124.

Omigbule, M.B. (2018). "Portraits of Arenas and Contexts of Understanding of Selected Ritual Performances in Ile-Ifẹ." *Ifẹ: Journal of the Institute of Cultural Studies*. Vol. 13. Pp. 38-68.

Ossai-Uloku, C.F. and Anyawu, C. (2024). "Traditional African Festival: Elements and Properties in Akashiede Kingdom's Ikenge Festival in Ukwuani Local Government Area, Delta State." *International Journal of Latest Research in Humanities and Social Sciences*. Vol. 7, Issue 5. Pp. 183-190.

Ọladiran, M.A. (2020). "Orò Pípè; Ètùtù Àtẹnuṣe nínú Ọdún Orò ní Ògbómọ̀ṣọ́."*Yorùbá – Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*. Vol. 10,No. 2. Pp. 61-75.

Ọpẹfeyitimi, J.A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-èdè*. Ile-Ifẹ: Ọbafẹmi Awolọwọ University Press.

Umejei, A.L. (2023). "Diaspora reconnection with homeland religion, cultural and heritage festival celebration." *Pharos Journal of Theology online*. Vol. 104, Issue1. Pp. 1-15.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** AKINDUTI, Taiwo Ọpẹyẹmi. Ìdálùú Nìṣèlú: Láríjà Àkóónú Ọdún Ìbílẹ̀ Ọ̀pá ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras*. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 188-201, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Akinduti, Taiwo Ọpẹyẹmi (jan./jun.2025). Ìdálùú Nìṣèlú: Láríjà Àkóónú Ọdún Ìbílẹ̀ Ọ̀pá ní Ìlú Osí àti Ìlú Ìpinṣà. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 188-201.